# Ẹtọ ati ojuṣe obi ti ọmọ ko si lábe rẹ

Ẹka ti ìranwọ ọmọ (DCS):

1. Ṣe ìdasile ati ìfirinle aṣe ìranwọ́ ọmọ ati awon ojuṣe ìranwọ́ ìlera.
2. Ṣe agbeyẹwó aṣẹ ìranwọ ọmọ fun atúnṣe ti o yẹ.
3. Gbà, ko si lẹ, ati pin awọn owó ìanwọ ọmọ pelu lilo Washington State Support Registry (WSSR).

**Obi ti ọmọ o si labẹ rẹ**

Obi ti ọmọ ò si labẹ rẹ ni o Obi ti ọmo ò si ni abẹ rẹ ni baba ọmọ, tabi baba ti o gba ọmọ tọ tabi ti ile ẹjọ pe ni baba ọmọ, ìya ọmọ, tabi ti ile ẹjọ pe ni ìya ọmọ tabi ìyá ti o gba ọmọ tọ ti o gbodo pese ìranwo owó fun ọmọ ti won ń tọ. Ofin ìlú ati ti ijoba àpapọ lo ṣe ni dandan.

**Awon ìsanwó ìranwọ ọmọ**

Lọ́pọ igba, wàá sanwó iranwo ọmọ. Leyin ti DCS ba fun ọ ni iwe ko sanwo iranwọ ọmọ, DCS **ko ni so pe o sanwó** si inu akoto owó rẹ fun awon ọwọ́ ti o ba san fun elomi ti o yatọ̀ si WSSR, ìlé idajọ ibilẹ̀ tabi abẹwẹ iranwọ ọmọ, tabi ìlẹ́ idajo ìlú mi tabi abẹwẹ iranwọ ọmọ. DCS ko ni so pé owó wo inu akoto owó rẹ fun owó ti won san fun elomi fun aṣe ofin iranwọ ayafi owó ti abẹwẹ san fun ẹni to lẹto si, gegebi Social Security Administration, Ẹka ti Labor ati Industries, tabi Ẹka ti Veteran Affairs fun ojuṣe iranwọ ọmọ.

1. Sọ fun DCS lẹsẹkẹsẹ ti ìlú mi tabi abẹwẹ iranwo ọmọ tabi ipinlẹ tabi ile ẹjọ ti ẹyà ba ni ki o sanwó iranwọ ọmọ fun awon.
2. Ma ṣe sanwó fun enikeni ti o yatọ̀ si adirẹsi WSSR ti won ko si isalẹ ayafi ti DCS ba so fun ọ ni kikọ pe won ti pari ẹjo rẹ.

O gbọdọ san gbogbo owó iranwọ si Washington State Support Registry (WSSR). Awon ọna ti o le gba sanwó ni:

1. Didin owó ti o ń gba kù. Ọpọlọpọ aṣe iranwọ fi aye gba ki DCS gba owó iranwọ pelu didin owó ti o ń gba kù tabi sisan si WSSR. Ti aṣe rẹ ba fi aye gba DCS lati ṣe bẹ, DCS ko ni gbiyànju ati gbá owó iranwọ ni ibi owó ti ọ n gba.
2. Iwe igba owó, aṣe owó, iwe igbawo ti o daju, tabi iwe igba owó ni ile ifowópáma. Fi iwe igba owó ati owó sọwọ si:
   WASHINGTON STATE SUPPORT REGISTRY
   PO BOX 45868
   OLYMPIA WA 98504-5868
3. Electronic Funds Transfer (EFT). EFT fi aye gba yiyo awon owó iranwọ́ ninu iwe igba owó tabi akoto ifi owó páma. Fun iwádi si, pé 800-468-7422.
4. Ẹrọ ayelujara. Ẹrọ ayelujara fi aye gbá yiyọ awon owó iranwọ nibi iwe ìgba owó tabi ifi owó páma. Fun iwadi si, lo òpo DCS ni https://secureaccess.wa.gov.
5. Kàádi ti o lowó lori tabi tabi ti ijegbéseé. Fun iwadi si, losi opo DCS ni https://www.dshs.wa.gov/esa/division-child-support/creditdebit-card-payments.

Ti ìlé iṣe ifowópáma ba dá iwe igba owó rẹ pada tabi ti ko ba gba EFT tabi isanwó lori ayelujara nitori pe aito owó ninu akoto, DCS yòò gba awon owó ọjọ iwaju pẹlu owó nikan, aṣe owó, iwe iyọ owó kuro ninu akoto, iwe igba owó ti o dáju, tabi dindin owo ti o n gba ku.

Fi namba akoto owó rẹ si **IN** ____________________ gbogbo owó sisan ati iwe.

Ti o ba ni idi ni abọ ofin ti ko mu ọ́ sanwó iranwọ fún awon ọmọ rẹ tabi ti DCS ṣe aṣíṣe pelu kiko ọ́ pọ, je ki DCS ma lẹsẹ̀kẹsè.

Ti DCS ba jẹ ki o mà pe awon da gbigba iranwọ lọwọ rẹ duro, wọn le gbaá lọwọ rẹ ni ọjọ iwaju. DCS yòó je ki o mà kòóto ṣe igbesẹ̀ yìí.

Ti o ba wa ni àhama tabi ọgba ẹwọn fun oṣu mẹ́fá tabi jùbèélọ, owó iranwọ ọmọ rẹ le dikù (duro) si $10 ni oṣu fun ọmọ kòókan. Iwọ, tabi alagbàtọ obi, tabi DCS le bèére fún idaduro. Ti idaduro ba ṣẹ́ẹ̀ṣe fun wọ, DCS yòó je ki o mà pelu alaye nipa idaduro na ati ẹtọ́ enikòókan lati bere fún gbigbọ alaye wọn ti wọn ko ba gba. Owó aṣẹ iranwọ na yòó lé pelu 50% ni oṣu kẹ̀erin ti wọn ba fi ọ silẹ̀, yi o si di 100% ti o n san tẹlẹ leyin ọdun kan ti wọn ju ọ silẹ̀.

**Ojuṣe iranwọ ìlera.**

Ti aṣẹ iranwọ rẹ ba niṣe pẹlu pipése ètò ilera fún awọn ọmọ rẹ, DCS yòó ri daju pe o pese rẹ. Ti aṣẹ iranwọ rẹ ba niṣe pelu ki o san owó ètò ilera, DCS yòó so eye owó ti wàá sán yòó si gba owó na.

1. So fun DCS lẹsẹ̀kẹsẹ̀ ti nkankan ba yi pada nibi ètò ilera awọn ọmọ rẹ gege bi o ṣe wa ni ibi aṣe iranwọ.
2. Owó iranwọ ilera ni dede ipin owó ilera ti wọn ko san ati owó ilera (owó sisán) ti o ba wa ni inu aṣe rẹ nigba ti ko ba si ipese fún ètò ilera.

Ti aṣe iranwọ rẹ ba ni ki eni ti ọmọ wa lodo rẹ pese ètò ilera tabi awọn inawó ti ko si ètò ilera fún, o le bere fun mimuṣe gbogbo awọn ètò iranwọ:

1. Bere lọwọ DCS fun mimuṣe ojuṣe eni ti ọmọ wa lọdọ rẹ ki o pése ètò ilera. Lori ọrọ rẹ, DCS le mu ojuṣé ṣẹ.
2. Bere lọwọ DCS ki o gba awọn inawó ilera ti ko si labe ètò ilera ati ajọsán, eyi ti wọn yọ, ati primiọmu bi WAC 388-14A-1020 ṣe sọ lati ọwọ obi ti o n moju to.

Ti aṣe iranwọ rẹ ko ba da lori ki obi ti ọmọ wa lodo rẹ pese ètò ilera, ipin ilera premiọmu, tabi ki o sán owó fún awọn inawó ti ko si ni abẹ ètò ilera, gegebi WAC 388-14A-1020 ṣe wi, o le bere lọdọ DCS fun atúngbeyẹwo aṣẹ rẹ tabi ki o kọ iwe fun ayipada fun ra rẹ.

**Oriṣi ẹhonu**

**Ìjokó apapọ.** Ìjokó apapọ jẹ ọna isakoso (ti kìí ṣe ti ile ejọ̀) DCS ti wọn fi n yanju aigbọraeniyé, ṣe alaye awọn imulo ati ti tan ina si ọrọ.

1. Ìjokó apapọ le ṣe agbeyewó aṣe ile ẹjọ̀ ati eyi ti kìí ṣe ti ile ẹjọ̀.
2. Ìjokó apapọ   Ti o ba ni ipade, o le ba alakoso DCS sọ eyi ti o le kọ̀ jale siwaju ipinu DCS.  Ìjokò apapo le yí igbesẹ oṣiṣe DCS pada ṣugbon ko le yi nkan ti ofin wi pada.

**Ẹto ile ẹjọ (igbẹjọ).**   Igbẹjọ nàá je ona (ti kìì ṣe ti ile ẹjọ) isakoso.  Igbẹjọ je ona ti o yatọ si ijokò apapọ sugbon ti o yatọ die si ẹjo ile ẹjọ.

1. Ofin ipinle pese fun gbigbo ẹjọ ni igbami.  Ti DCS ba fún ọ ni iwe, iwe na yòó sọ fun ọ boya ọ ni ẹtọ si ki o rojọ.  Adajọ ofin ti isakoso (ALJ) ni yòó jokó lori ẹjọ na.  Awọon ALJ kii ṣe oṣiṣẹ DCS.
2. Ti ẹjọ ba nlo lọwo, ALJ le yẹ ẹjọ rẹ wọ ti yòó si dajọ lori ọrọ rẹ.  Lati da DCS duro ki wọn ma muṣẹ aṣe iranwọ ọmọ, o gbọdọ pé fún igbẹjọ láàrin ogun ọjọ (ti o ba gba iwe ni ìlú Washington) tabi láàrin ọgọta ọjọ (ti o ba gba iwe nita ìlú Washington) leyin igba ti o ba gba iwe.
   a. O le pe fun igbẹjọ láàrin ogun tabi ọgọta ọjọ.  Ṣugbon, DCS ko ni muṣe aṣe iranwọ́ rẹ afi ti o ba gba iwe idájọ. DCS ko ni da owó kankan pada ni asikò ti o n dúró de iwe idájọ.
   b. Ti o ba pe ẹjọ leyin ọdun kan ti o gba iwe, oo ni lati fi ìdì pataki hàn ti o fi pẹ́ bèère.  ALJ le ma dahùn si ibèérẹ rẹ. Ṣugbon, ọ le ni ẹtọ lati yi ojuṣe iranwọ ọmọ rẹ ọjọ iwaju pada kó dà ti o ba ni idi pataki fun pipẹ bèere igbẹjọ.
3. Wọn a fi ránṣe si ọ ẹ̀da idajọ ALJ.  Awọn ẹtọ̀ọ rẹ lati pe fun ẹjọ kọ̀tẹmilorun yòó wa ninu idajọ ALJ
4. Ti o ba ṣéèṣe, DCS yòó sọ fun apa kini ati ikeji si aṣe iranwọ rẹ nigbati a ba gba ibèére fun igbejọ.  Apa kini ati ikeji le kopa nibi igbẹjọ.

Ti o ba ni ibèére:
ẸKA TI ÌRANWỌ ỌMỌ (DCS)
PO BOX 11520
TACOMA WA 98411-5520

Ninu __________________________ pipe agbegbe ________________________

Nita __________________________ pipe agbegbe ________________________

TTY/TDD wa fun eni to kọ ba le sọrọ tabi gbọrọ dáada.
Lọ si opo wa ni: www.dshs.wa.gov/esa/division-child-support

| |
|---|
| Kosi enikeni nitori ẹya, awọ. oriléede, igbagbọ, ẹsin, imọ ọkunrin tabi obinrin, tabi akànda, ni wọn ya sọtọ ni idi iṣẹ, tabi nibi ẹka kan etọ yìí. Pelu ibèére, fọọmu yi wa ni ẹda mii. |